# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No 766 MONDAY AUGUST 10 1964 (2D)


## Ọlọla Azikiwe Ti Nni Igbadun Ninu Aisan

NSUKKA:- Laipẹ yi ni irohin de ọwọ wa lati Nsukka ilu Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe ni a gbọ pe ara rẹ ko ti da lati nkan bi oṣu mẹrin sẹhin nibi ti o ti lọ fun isinmi oṣu mẹfa eyi Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe nlo ni ilu rẹ ni Nsukka ni ipinlẹ Ila Orun Naijiria

Irohin na tun fi ye wa pe Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe ti gbadun bayi, Irohin na tun fi ye wa pe Dokita arẹ ilẹ Naijiria to nṣe itọju rẹ ni ile rẹ ni Eko.

Dokita H. I. Idehen yio lọ si Nsuka larin ọsẹ yi lati lọ wo gẹgẹbi Dokita Nnamdi Azikiwe ti nle si atipe Dokita Idehen yio tun ṣe Abewo gẹgẹbi Dokita Azikiwe ṣe ri atipe yio tun fun ni awọn ogun ti yio tete jẹ ki Arẹ ilẹ Naijiria Dokita Azikiwe le tete ni Igbadun ti o daju dada.

Irohin na tun fi yewa pe ko si ọrọ to le mu ibẹru wa fun arẹ Ọlọla Dokita Azikiwe ti ara rẹ ko da bayi. Awa Oniwe Irohin yio jẹ ki ẹtun ma gbọ gegebi ara Dokita Azikiwe ṣe nle si ti ẹba nka Irohin Imọlẹ lojolumọ.

# ỌLỌPA GBOGUNTI AWỌN ỌMỌ LẸHIN AWOLỌWỌ?

EKO:-Gbogbo Ile ẹjọ kekere kan ni ilu Eko lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gbero fun ogunlọgọ okẹaimọye enia ti nwọn wa si ile ẹjọ na nigbati awọn Ọlọpa mu awọn enia mẹta kan ọgbẹni Ọlatunji Fasanya, Azeez Dada ati Adam Ọtẹkọya wa siwaju adajọ Agba Oloye A.S.E. Agbabiaka ni opin Ọsẹ to kọja yi, fun ẹsun pe, wọn kigbe pe oloye Awolọwọ ni ni gbangba ode

Ẹsun ti ọlọpa ti o ba awọn enia na ṣẹjọ ka si wọn lẹṣẹ ni wipe, ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi, ti ọlọla Alhaji Abubaka Tafawa Balewa, Alakoṣo Apapọ Ijọba Naijiria pada de si Eko.

Nigbati awọn ọlọpa ati enia ti o wa pade Alhaji Balewa lọna, nrekọja lọ ni Gbangba ọdan l'Eko, ni awọn enia na ba nkigbe ni ohun rara pe, "Awo! Awo!! Awo!!!

Ọlọpa na tun se alaye siwaju fun Ile ẹjọ pe, lẹsẹkẹsẹ ti awọn enia na npariwo "Awo" le Balewa lẹhin, ni awọn ba da motọ duro, ọrọ di pẹntuka, ni awọn enia na ba fẹsẹ fẹ ẹ nwọn si tuka yanga ṣugbọn ki awọn enia na to salọ jinna ọwọ wọn tẹ mẹta ninu wọn awọn si mu awọn mẹtẹta na lọ si tesan lẹsẹkẹsẹ.

ṣugbọn nigbati awọn ọlọpa



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

na tisọ gbogbo ọrọ wọn tun niwaju adajọ ni awọn enia na ba sọ ṣako gbangba niwaju adajọ pe, awọn lo jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa mu awọn wa si ile -ẹjọ fun.

ARIYANJIYAN

Ṣugbọn ki awọn enia na to sọrọ tan, ni Ọgbẹni John Oyeyi, ọkan ninu gbajumọ Agbẹjọro atata ni igboro Eko ba dide ti o si gbẹsẹ fun awọn enia na.

Ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Oyeyi, sọ gbangba niwaju adajọ pe. Ile ẹjọ gbogbo fi iwe pe Alhaji Tafawa Balewa, wa si inu Ile ẹjọ na ki o si wa fi ẹnu ararẹ sọ, gẹgẹbi ọrọ na ti ri.

Ọgbẹni Oyeyi ni on da ni imọran fun ile ẹjọ pe ki o tete yara tete fi iwe ranṣẹ si Balewa lati wa sọ gegẹbi ọrọ na ti se lọ ni ọjọ na, nitori agbedemeji ara rẹ.

pe "Ofin ko mọ ẹnikan ati pe bakanna ni gbogbo enia labẹ ofin".

Ṣugbọn Oloye A. S E. Agbabiaka tiṣe adajọ Ile ẹjọ kekere na sọ pe Ẹ hẹrẹ ẹfẹ ọrọ yẹyẹ ati awada lo sọ,

DURO

Lẹhin ariyajiyan diẹ to wa larin ọgbẹni Oyeyi ati Adajọ nipa pe, ki Ile ẹjọ paṣẹ pe ki Balewa wa jẹri ni kotu ti adajọ si ti ko fun wọn ati eyiti o ka si ọrọ ẹfẹ

Ọgbẹni Alubi Maṣha, ti ise ọkan ninu awọn Agbẹjẹro awọn enia na, tun dide o si gbe ọrọ na lẹsẹ pe, ofin ko mọ pe ẹnikan wa ni aye to ga', bakanna ni gbogbo enia ri labẹ ofin.

Lẹhin ti adajọ ti fa igi le ọrọ na tan' ni awọn enia na wa bẹbẹ pe. ki adajọ gba iduro wọn, ki o mase fi awọn enia na pamọ si itimọle awọn Ọlọpa.

Ṣugbọn ọgbẹni Augustine Okebi, ti iṣe Agbẹjọro fun Ijọ , rọ ile ẹjọ pe, ki adajọ maṣe gba iduro awọn enia ki nwọn si wa ni itimọle awọn ọlọpa titi di ọjọ ti adajọ yio ṣe idajọ wọn



Alhaji Abubaker Tafawa Balewa
Alakoso Ijọba Apapọ

Ọgbẹni Okebi, tun ṣe, alaye fun ile ẹjọ pe, "Bi adajọ ba gba iduro fun awọn enia na, nwọn ko ni jẹki Balewa oma a rin kakiri ilu, gẹgebi o ba ti ṣa fẹ nwọn osi ma yọ lẹnu"

Ọgbẹni Okobi tun ṣe ala ye fun ile ẹjọ pe ki adajọ


Wo Oju Ewe Kẹfa




Alhaji D. S. Adegbenro
Asiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre

# Agbọradun

Lati Ọwọ ỌMỌTAYỌ

SI AWỌN ỌDỌ-MỌDEBINRIN

Mo ki nyin ẹ ku owurọ ara le tabi ko le? Ajinde ara yio ma jẹ fun gbogbo wa o (Amin.)

Ni ijerin mo ṣeleri pe emi yio ba awọn ọdọmọbinrin wa sọrọ, ọrọ mi na jẹ bi Imọran nitori ti a ba wo iwaju ti a wo ẹhin ao ri pe pupọ awọn Ọdọmọbinrin ni nwọn ti kanju jẹ aiye ti nwọn wa nkabamọ igbesi aiye wọn na Nitori idi eyi mo kesi ẹnyin Ọdọmọbinrin pe eyikeyi ti o ba ka Imọran mi yi ki o lo wo Iwọ yio ri bi yio tiṣe rọrun fun ọ ni gbesi aiye rẹ.

Mo fẹ ki pupọ ninu nyin tọrọ suru lati ọdọ Oluwa Oluda nyin ṣebi pupọ ni o ri ninu awọn Ọdọmọbinrin ti o ti ko'le ti osi nfi mọto ṣe ẹsẹ rin kilo fa ? Lọwọ suru ni, ẹdakẹda to ba ni suru ni ohun gbogbo tan nitori mo fun nyin ni imọran fun ilọsiwaju igbesi aiye nyin.

Idi ti o ni lati fi ni suru ti o ba fẹjẹ aiye irọrun ni pe ti o ba jẹ ọna ti iwe kika ni ka a de ibiti ẹru ki yio ba ọ ti o ba si jẹ ti iṣẹ kikọ ni kọọ bakana,sugbọn ki o mọ daju pe kiṣe ọjọ ti o di ominira ni iwọ yio ti ma ṣe ifẹ inu rẹ iwọ yio ma wo nwọn Ọlọ bọn ti o nbẹ niwaju rẹ bi nwọn tiṣe nlẹsọ jaiye wọn laiṣe aniani iwọ na yio ba wọn jẹ aiye pẹ.

Ẹnyin Ọdọmọkunrin ti ẹ fi ikanju bimọ mo fẹ ki ẹ mọ daju pe aye si wa fun ọ lati le ṣe ala iwọ yo tun pada lọ si ilewe ni tabi ti iwe rẹ ba ti to tẹlẹ ki o to bimọ ki o tete bẹrẹsi wa iṣẹ kiri nitori ọwọka nko gbe ẹru d'ori lode oni. ti o ko ba mọ bi aiye yi ti jẹ lode oni ṣe iwadi lọdọ awọn obi rẹ

Nwọn a sọ iriri wọn fun ọ ki o gbọ, ti o ba nireti pe ọkọ rẹ ni yio wa ṣe ohun kohun fun ọ, ọkọ rẹ na le se ileri fun ọ nigbati o wa lọna sugbọn ti oba ti di iyawo ile ti oba na ri gba ninu ile ri ti o ṣe fun ọ kole ju ẹyọkan, sugbọn ti o ba ni iṣẹ tirẹ ni ọwọ mọ daju pe yun gba ni ile nyin yio ma dun bi ile oloyin ja ko ni si awọn ọmọ nyin yio ma kun fun ayọ ni ṣugbọn ti o ba gbojule pe ọkọ rẹ ni yio ma ṣe gbogbo inawo ile arẹ ati irẹwẹsi ko ni pẹ de si irufẹọkunrin na.

### ỌRỌ AGBA

Ọrọ agba ti ko ba ṣe ni owurọ yio ṣe ni alẹ,

Ọlaju ti jẹki a padanu ohun rere tẹle ri ifarabalẹ lo ma mu ki awọn obi wa ba

# Itumọ Ala

A. O. Yesufu Lagos Ala buburu ni eyi, awọn ẹlẹiyẹ lo nle ọ kakiri loju ala lati ṣe ọ ni jamba, ṣọra gidigidi.

A. G. Arena Box 89 Mushin Ala buburu ni eyi, ṣọra nipa ija, ki o ma ba lu ofin Ijọba ti o le mu ọ de ọgba ẹwọn

Amos Tunji Abeọunde Street Micheals School Esiẹ Via Ọffa Ṣọra gidigidi, awọn ẹlẹiyẹ lo nfara han ọ loju ala yẹn, a'a buburu ni, sọra ki ọwọ wọn ma ba tẹ ọ Adura ni ẹbọ.

M. A. Ogunbayọ Box 20 Ilaro Ala yi ko dara ṣọra lọdọ alakowaba.

Timothy Odumeri United Sec. Mod. Sch. Ṣagamu Ṣọra nitori jamba airo tẹlẹ.

Tọlani Akinfenwa 70 Olushi Street Lagos Ṣọra ki o ma ba mu amubọ lasiko yi.

Alanni 23 B Okearin Street Lagos Alagba nko ri iwe rẹ ka dada, lọ be ẹniti o mọ iwe kọ ki o ba ọ kọ

Bisiru Kẹhinde Edidi 9, Giwa Street Odi-Olowo Ṣọra lọdọ awọn ẹlẹtan Ọbinrin ki nwọn ma ba lu ọ nijibiti

Ajọṣẹ 58, Apọngbọn St Lagos Ala rere ni eyi, maṣe bẹru, ohunkohun ti o ba dawọle rere ni yio jasi

S. Ipinaṣẹ Ọmọ Otun O o Ṣọra ki o ma ba padanu ohun ti o sọwọn fun ọ.

# 'Irohin Imọlẹ' Mo Ba Ọ Yọ

Lati Ọwọ ẸRUKOBODO Eko.

"Ẹniti a lero wipe kole pagọ, o ṣe bi ere bi ere o di alaruru," ni ohun ti o tọ'fun mi lati fi ṣe ẹsin iwọnba ọrọ ti ng'o fi ki Alakoso ati Olotu "Irohin Imọlẹ" ti o goke agba di ọmọ ọdun kan ti a ti nri ka lojoojumọ yika igun mẹrẹrin ilẹ Naijiria ati ilu okere.

Ohun to mu mi kun fun ayọ ati ọpọlọpọ ọpẹ fun Ọba Olodumare to da ẹmi wa si di asiko ti a mba Alakoso Iwe "Irohin Imọlẹ" yọ yi ni wipe, emi "Ẹrukobodo" jẹ ọkan ninu ẹniti o ra "Irohin Imọlẹ" na ni ọjọ ti iwe Imọlẹ Irohin na kọkọ tan jade ni orilẹ ede Naijiria ni ọjọ kẹta ọsu July 1957 ati pe, ọjọ na si tun jẹ ọjọ ayọ nla kan fun mi, ntori pe, ni arin ọrẹ ati ni arin ojulumọ ti mo ṣe sibi idawọ ọmọ kekere alejo aiye kan ti Ẹleda fi tami lọrẹ lọjọ na ni iwe Imọlẹ Irohin na tan wa ba mi.

### OLUWA KO RAN ALAKOSO LỌWỌ

Lẹhin ti mo ka iwọ ba irohin to mbẹ ninu Irohin Imọlẹ ọjọ na tan, adura atọkanwa mi lọjọ na ni wipe ki Oluwa ko ran Alakoso Irohin Imọlẹ na lọwọ debi wipe ki Irohin Imọlẹ rẹ na o le maa jade lojojumọ a i pe ki ọmọ ti mo bi lojọ na si dagba ba Irohin Imọlẹ gegebi iwe Irohin l'ede Yoruba to kọkọ jade lojojumọ nilẹ Naijiria mo dupẹ lọwọ Ọlọrun to gba adura mi, nitoripe lati ọjọ kọkandinlọgbọn osu keje 1963 ni Irohin-Imọlẹ ti njade lojojumọ ati pe ọmọ ti mo bi lọjọ ti Irohin Imọlẹ kọkọ jade (3/7/57) si ti dagba bikotilẹ ti le mọ Irohin Imọlẹ ka dara - dara mo dupẹ lọwọ Ọlọrun fun w pe ọmọ na ti mọ ohun ti nwọn npe ni Irohin Imọlẹ ati wipe oti ri wipe lojojumọ lo njade ati pe o tun mọ Olotu Irohin Imọlẹ na ni a mọ dunju eyi jẹ ohun pataki ti o mu i mi dun lati ba Alakoso Irohin Imọlẹ yọ ayọ nla na fun ase yanri ati a se loriyin. Ki Oluwa ko bukun iṣẹ rẹ.

### IMỌRAN

Ohun pataki ti emi "Ẹrukobodo" fẹ fi siwaju Alakoso "Irohin Imọlẹ", gegebi imọran ni wipe:- A ti ri i daju wipe "Irohin Imọlẹ" ti ati lero wipe kole pagọ, ti o ṣe bi erebi ere ti o di ẹniti o nkọle alaruru (Pẹtẹsi) loju awọn iwe Irohin Lede Yoruba yoku, Eyi ti Ọlọrun ko ni da pada sẹhin mọ lailai.

Imọran mi na ni wipe, oto asiko ti ewe inu iwe Irohin Imọlẹ ti o ti jẹ mẹfa ko yi pada di mẹjọ ki a si ma raa ni Tọrọ (3d) gẹgẹ bi a ti nra awọn iwe Irohin yoku nilẹ Naijiria mo ki Alakoso Olotu ati gbogbo awọn osiṣẹ rẹ fun ajọse Ọdun kan ti Irohin Imọlẹ ti njade lojojumọ nilẹ Naijiria.

Aṣẹ ye ni Alakan nṣe epo ẹko ni ṣe e ti l a gb a r a Odumare.


## ỌJA TITUN

Oṣẹ Arikisiki 10/6, Oruka Iṣẹgun Ọta 10/6,
Ibere Iṣẹgun Aje 7/6, Isoyẹ Ọmọ Ilewe 10/6,
Turari Iṣẹgun Aje 5/-, Ọṣẹ awure Owo 10/6,
Ogun Narun 21/ Ogun Ẹda fun Obinrin 21/-

Kọwe si 'Bukoye & Son c/o Mapo Box 3142,

IBADAN

# IWE SI OLOTU

## Mo Kan Saara Si Ọmọ Omupo

**Nba sọpe bi Olotu ba le gba mi ni aye lati dupẹ lọwọ awọn ọmọ ilu Omupo fun akitiyan ati akikanju lati pe awọn agba gbogbo owo ti ẹnikọkan wa bajẹ ninu ilu Omupo to wa ni Eko,**

Moki ẹni to mu Imọran na wipe ki ẹgbẹ Ilọkan mu enia mẹrin wa fun Ikiri owo na awọn ọmọ ilu Omu tise eyi tipẹ atiwi pe to ba ṣe pe awọn ọmọ ilu Omupo bafi nkun owo bayi ele- ni nkan kọba ma dara ṣiju ele yilo Ninu Ikiri nani ẹgbẹ orẹ mẹta ti se ileri pe ipa isẹ Baba wa ti ise agbẹ Amuludun ni ao mate le atipe ao ni fi owo jẹ awon to nkiri nale niya -ara botileje pe awọn kan nsọrọto tabuku ati awon tosọpe kini awọn ẹgbẹ orẹ mẹta yio se? Sibẹ awa ẹgbe orẹ mẹta dupẹ ninu ọrọ akọwe egbẹ nao Ọgbẹni R A Bakare Nigba gbogbo ni ao ma se agbara gẹgẹbi awọn Baba wa ẹkbẹ Amulndun ti se adura fun wa ao ri pe nkan nlọ dede wipe awon to ngba owo na ri owo na gba lasiko Ti abatun ri egbẹ Amuludun ni Iwaju wako si ifoya kankan rara atimope gegẹbi Baba ati omo ni enikẹni mo si Bakana awọn ẹgbe orẹ meta kan saara si Baba wa Samuel fun akikanju to nse gẹgẹbi ati ṣe lagbara mọ ori ki ilu Omupo dara Oluwa yio se tirẹ bẹ

Motun bẹ awon ọmọ ilẹ Omupo kiẹ ma se sa fun awọn to ngba owo kiẹ si gbiyanju Oluwa yio bo aṣiri olukuluku ati towa ni ile Apapa Surulere Ibadan Kano ki wọn tete fi owo owo na tanṣẹ fun ilọsiwaju ilu Omupo ati pe ki o ma di pe a nle r'awa bi ẹn ngba owo ori ki a to le da owo fun ilosiwaju ilu wa Mo tun ki awọn baba wa ẹgbẹ Amuludun lori ilu Omupo le dara,

To ba jẹ pe iru ẹgbẹ na to mẹta ko ba ti si iru edeaiyede larin ilu wa nitoripe wọn nmọ eto pupọ lori ilu na ati pe opọlọpọ enia ni ilọsiwaju ba ti wa fun ni ilu Omupo. Mo si tun gbọ pe awọn kan nso orọ ti ko tọ si awọn ẹgbẹ Amuludun ati awọn ti ngba owo na ati pe nwọn ngba owo ẹhio lọwọ ẹgbẹ ọrẹ mẹta, Mo fẹ fi ye nyin pe ẹrọ na ko rihẹ rara ati pe ti e mọ pe iyẹn o jẹ ki ẹgbe Amuludun ni ifẹ awọn ẹgbẹ mẹta irọ ni patapata,

Mo fẹ ki awon enia na tun gbiyanju lati wa fun ilu Omupo lowo fun ilosiwaja ki nwọn le ni ifẹ nyin Emi ko fẹ ki a fi enu ma sọrọ si ara wa, Nigbati ati sọ pe irepọ la ufe ko to ki a ma tabuku fun ara ati fun ogo ilu wa

Mo tun kan saara si ile Nana Agbaji ati awọn oke mite lori ilọsiwaju ilu wa, Mo tun ki ara adugbo ni Oke Omu ati Isalẹ Omu Mo tun bẹ awọn ẹgbẹ ti ko yoju lati ṣe dada ati lati da owo fun awon to ngba owo na Ilu ti ko to Omupo nwọn fi owo nilẹ dada ati pe owo ti nwọn nda o ju ti wa nitori ni ilu miiran (5) Ṣugbon nitoripe awa po ni owo na ṣe mọ be Mo tun ki awọn ara ilu Omupo lorukọ ẹgbẹ mi ọrẹ mẹta atuwa jẹ ki a ko ere oja dele amin,

Mo dupẹ pupọ o, Olotu ọkọ Ọbẹ ko ṣa nyin lẹsẹ ami ,

Emi ni
A Adio Bakare
OMUPO

## E Da ẹgbẹ awọn Ọṣiṣẹ Silẹ

Olotu, Ẹ jọwọ e gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ oloyinmọmọ lati sọ ọrọ mi kekere yi fun awọn oṣiṣẹ ilẹ Naijiria ki nwọn si tete fi si ero.

Ọrọ mi na ni wipe, ki nwọn tete jẹki a da ẹka ẹgbẹ Oṣiṣẹ ti nje (Labour Party) silẹ ni jakejado ilẹ Naijiria ki iroyin ba le wa fun gbogbo awọn oṣiṣẹ ti o wa ni ilẹ Naijiria.

Ti gbogbo awọn oṣiṣẹ Orilẹede yi ba le parapọ da ẹgbẹ ti nje (Labour Party) yi sile, a o ri mọ wipe ko ni si iṣẹ dida silẹ mọ. gbogbo awọn oṣiṣẹ Orilẹede yi ni yio si ma ni ajẹyo ati ajẹ sẹku silẹ. Nipa bayi awọn opọlọpọ enia yio ri owo ran ọmọ wọn ni ile ẹkọ giga

Gẹgẹbi ẹyin na ṣe mọ wipe iru ẹgbẹ yi wa ni ilu Oyinbo ti wọn si ma ndibo fun wọn laseko idibo, yio dara pupọ ti awa na ba le da iru ẹgbẹ yi silẹ ni ilẹ Naijiria.

Inu wa yio si dun pupọ ti awọn asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ ilẹ Naijiria ba le mura si ọrọ na ki awa na le ni ẹgbe oṣiṣẹ Oṣelu (Labour Party) ni Orilẹ ede yi ki awa na le ma dibo fun wọn ni asiko idibo.

Olotu, mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi, Ẹ ku iṣẹ o,

Emi ni,
S. O. Famiyẹsin, "Rico Boy",
MUSHIN.

## Angbadun Itan panpalaṣo

Olotu Irohin Imọlẹ inu mi yio dun pupọ bi ẹ bale gba mi laye diẹ lati ki Ọgbẹni Shoyinka fun itan tuntun ti o bẹrẹ si kọ sinu iwe Irohin yin

Awa ti awa ni Ikirun ati agbegbe rẹ gbadun itan na pupọ ṣugbọn yio jẹ nkan ti yio wulo pupọ fun awa ọmọ Yoruba bi Ọgbẹni Shoyinka bale gbiyanju ati se iwe jori Itan yi bi ogboju ọdẹ ninu Igbo Irumọlẹ ti D O Fagunwa ṣe

A o ma reti iwe itan na lati ọwọ Ọgbeni Shoyinka
Olotu araṣe yio ma bayin o

Emi ni
Ọladeji Latubọsun
IKIRUN


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patroise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Prnting Press**

**16 Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI





**ALE-BI-ELE** Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọgbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbó ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" ngbakugba yio salọ pẹlu igbaaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# Bi ao ku işe ko tan

LATI ỌWỌ J. FỌLABI ATOYEBI

Mo ki Olotu pupọ wipe ẹ ku owurọ, Oluwa yio jẹki ọwọ nyin ma lọ si oke o. Iwaju ni ẹpa ẹbiti nresi o. Oluwa ko ni jeki ọkọ ẹba ko ni şan yin ni ẹsẹ o, amin ati aşẹ. Ẹjọwọ mo fẹ ki ẹ gbami ni aye ninu iwe yin olo-yinmọmọ ti nte bi akara gbigbona lati gba awọn ara olu-fẹ, ẹgbọn ati aburo ni iyanju pẹlu ọrọ mi kekere yi.

Ẹnikẹni ti o ba kọ akọle ini yi, yio mọ wipe owe awọn agba Yoruba ni o sọ bẹ. Ti a ba si tun fi oju inu wo, a o ri wipe owe ti o jinlẹ ni. Ni akoko, Ẹ jẹki a sọ ọrọ nipa owe na ohun ti itumọ re jẹ ... na ba awọn ti o jẹ wipe nwọn ma nrọ ọ ọ lọ siwaju ti nwọn ki i si ro lọ si ẹhin wi, ti ohun işorakanba de ba wọn

...wa ẹda gegẹbi ẹleran ara tişe wa laiye yi, ko le şe alai pade isoro bi aini, airi jẹ airi şẹ şe, airi aşọ wọ tabi awọn nkan ba wọn-ni. nigbati a ti mọ wipe a ko le şe alaimapade ohun bawọnni ninu igbe aiye wa, a ni lati ma ro ni iwọntun-wọnsi iru ipo ti a wa nigba-na si ti o m ọ ẹrikeji wa. Boya ti nwọn san ju tiwa lọ.

Nitorina ẹnyin ara, ẹjẹki a w a n i itẹlọrun p ẹ l u i p o k i p o ti a b a w a tabi ohun ti o ba nsẹlẹ si wa gẹgẹbi igbesi aiye wa na tiri, Nigbakigba ti a ba si wa ninu isoro ẹ jẹki a ma ranti ọrọ orin ti o sọ wipe "Ki a d ro de irawo rẹ ti o ba tilẹ pẹ ki a duro, bi ilerina tile falẹ şugbọn ko ni pẹ de. Ati eyiti o sọ wipe ẹda tomọla kosi.

Nitoti anri ọpọlọpọ ẹda ti o wipe nigbati nwọn ba wa ninu isoro nwọn ko ni ero miran ju wipe ki nwọn lọ pokunso tabi ki nwọn ge ara won lọrun nwọn ti gbagbe wipe awọn ko le da ara wọn ati wipe awọ kọ lo da ẹya ara wọn şe, Nitorina iwọ ẹda maşe ro ara rẹ pin, nitori iwọ kọ lo dara rẹ ati wipe nigbati iwọ ko reti iranlọwọ rẹ Olugb-ala yio de

Nitorina gbogbo wa gẹgẹ bi onigbagbọ ododo, ẹ jẹkia ma ni suru lati duro de asi-ko ti oluwa. Nitori bi aba bẹrẹ ohun kan ni ọwọ rẹ ti ako si ti ri gbọ, Ki a ranti wipe On jo da wa awa si ni ẹda ọwọ rẹ o mọ ohun ti o yẹ wa ye ogo rẹ yio si şe fun wa Ẹjẹki a ranti wipe bi ẹku pe di alẹ sugbọn ayọ nbọ li owurọ. Nitorina ẹ yin ẹda alaye ẹ jẹki ama mu suru de Oluwa nitori asiko tirẹ l ju

Mo dupẹ pupọ fun aye ti ọ gba mi ọwọ yin yio ma lọ si oko. Ti Ọlọrun ko ba kọ işẹ ẹru rẹ emi yio tun ma ba nyin sọrọ ni aipẹ yi

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan. 20-Feb. 18) Nwọn o, mu irohin buburu kan wa fun ọ loni. Maşẹ binu lojiji ki o ma ba Şiwahu.

PISCES (Feb 19 March 20) Itẹlọrun wa fun ọ loni lẹnu işẹ ati ninu ile pẹlu.

ARIES (March 21 - April 20) O gbọ irohin ijaiya kan loni ti ko ni jẹ ki opa ọkan pọ si oju kan. Maşe sọ ireti nu.

TAURUS (April 20-May 20) Ọjọ oni dara fun ọ lati lọ şe ibẹwo awọn ọrọ rẹ. Şọra pẹlu owo olowo

GEMINI (May 21-June 21) Ọran owo kan wa niwaju to mu u rẹ loni Ọjọ oni si tun dara fun ọ lati lọ si oke Okun.

CANCER (June 22-July 22) Işẹ pupọ wa fun ọ lati şe lori şọra pẹlu işẹ aşeju nitori aisan,

LEO(July23-Aug22)Ilosiwaju wa fun ọ loni.

VIRGO Aug23 Sept22)Gbiyanj lati sunmọ olufẹ rẹ dasda loni maşe jẹki okun ifu to wa larin yin o ja o.

LIBRA(Sept23-Oct23)Id mu diẹ wa fun ọ loni ti ko ni fi ọkan rẹ balẹ.

SCORPIO(Oct24-Nov22)O şe alabapede awọn enia kan ti o se iranlọwọ fun o loni ti o ko ba kọ kan ti nwọn fẹ pe ọ si.

SAGITTRIUS(Nov23-Dec21)Ilọsiwaju ati orire wa fun ọ loni Maşe lo asiko rẹ lori ohun ti o ko şe pe iptr-nu le lori,

CAPRICORN(De22-Jan19)Gbiyanju lati ri awọn ti o nyan lodi ki o si işorọ rẹ han wọn Nibẹ ni iranlọwọ wa fun ọ


HELLO ! HELLO !! HELLO !!!

**OLUSHI SOCIALISTS**

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

**at Foresters Centenary Hall**

22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p. m. till dawn

*MUSIC BY*

**New Time Enterprises Bashy & His Young Stars Orchestra**

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

**Bar Bar Inexhaustible**

**Tickets 3s Flat**

Tickets obtainable at 16, Bamgbose Street Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos



MAFI OWO RẸ ŞE "OFO" MỌ NIPA RIRA AWỌN KỌBIRỌBI TỌNIKI NITORIPE OWO WỌN RỌJU ARA RẸ LO NSE IYẸN DAJU O BERE OJOLO AO H UNHAUN AYONRAN TỌNIKI TI WỌN NPE NI

# "MINOPHOS–TONIKI"




Aworan ẹgbẹ yi fi han ọ gbangba bi ẹda eni ti ri laisi "ẸRAN ARA" ẹtlpe ojulowo tọniki to le şe işẹ ribiribi ni ẹjẹ ara, işọri ara ninu egungun gegẹbi awo-ran yi to fi han ọ, MINO-PHOS Tọniki a ma ẹje fa ti-tun si ara, papa ti e ia ba nru siogurodo tabi fun wa-hala işẹ şişe aiko nri orun sun daradara to, beni o si darajulọ pelu bi ara enia ba ngbona nigbakugba ta-bi lehin aisan tabi amodi bi igbona, iba pọ jupọnju tabi a ... wi vo enia nigbaku gba,

At fun işọn a lokun ati egungun ara ti o ba dabi eni-pe omurọ tabi ti ko la gbara to. Şi dan igo kan egbogi tọniki yi wo iwọ yio si ma rohin rẹ fun gbogbo enia pẹlu. Bere ni Şọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
WATERLOO (SHOP) MEDICINE STORES
8, PALMCHUCH STREET LAGOS
P. O. BOX 333

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE AUGUST 10 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ọbun—Eko, Ojuwoye, Atan, Agbabo, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Pẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta, Ijaiye—Orilẹ |
| IJẸBU | Iishan, Odogbolu, Atan, Imọpe, Işara, Imọdi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaşẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado—Odo |
| EKITI | gosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ IŞẸGUN AUGUST 11 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUT | Mushin, Badagry Ọtta, Abalabi, Şodẹkẹ Omi Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Şojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwn Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idoko Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owooe |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ'RU AUGUST 12 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajọ Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọ |
| ABẸOKUTA | Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Igbo-Ọra |
| IBADAN | |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Işara, Imodi Ijẹbu-Ijẹsha |
| IJẸSHA | Iwara Ejirọ, Odo, Ibokun, Lasilo Idiẹmi |
| ẸGBADO | |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ AUGUST 13 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUT | Oyingbo, Ijoko, Ibẹrẹkodo, Aşu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Şagbẹ, Ogunjau, Motolẹlẹ, |
| IJẸBU | Aiyepe, Şagamu, Itaoşu Ogere, Irolu, Itelu Ode-Rẹmọ Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunw Iboro |
| ẸGBADO | |
| EKITI | Ilogbo, Ishan. |

## ỌJỌ ẸTI AUGUST 14 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUT | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Işabọ Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| BADAN | Fẹdẹgbo, Oyedededeji Ogburo, Ẹgbẹ B balokuta. Ijaiye-Ọrile |
| IJẸBU | Iishan, Işara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ Iọbnlmuroko, Erinm |
| ẸGBADO | Ayetoro Ado-Odo |
| EKITI | Egosi Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ ABAMẸTA AUGUST 15 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Mushin, Ọtta, Abalabi, Şodẹkẹ, Omilda Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun —Ọwa, Ẹruwọn, Omu, Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko Itoko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ AIKU AUGUST 16 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ ABẸOKUTA | Ikẹja, Agege Ebute—Ikorodu Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajlde Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, |
| IBADAN | Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Işara, Imodi |
| IJẸSHA | Iwara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilọ-Idiẹmi |
| EKITI | kemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ AJE AUGUST 17 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBERẸ ABẸOKUTA | Oyingbo, Ijoko, Bẹrẹkoko, Aşu, Wasinm, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Şagbẹ Ogunjau Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoşu Ogere Irolu Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla Imẹsi-Ile Alagba, Ilaro, Ọja Ọdan, Sunwa Iboro |
| ẸGBADO | |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ ƐJO'NGBORO

### MBASI

Awọn enia ilu Eziuihite Ovoro ati Ahiara ti o wa ni ajumọsepọ kan ti da owo ti o to bi £14,000 lati le fi bẹrẹ eto isẹ omi ẹrọ mimu kan fun awọn agbegbe ilu meji na ni ẹkun Mbasi ni ipinlẹ Ila-Orun Naijiria Eto owo ti awọn ara ilu na ko jọ si wa fun eto iranlọwo ti awọn ara ilu na şe lati fi ran ijọba ipinlẹ Ila Orun lọwọ fun eto isẹ omi na.

### IKẸJA

Ni ọjọ Ẹti ti işe ọjọ kejeosu yi ni ọga agba awọn Ọlopa ilẹ Naijiria şe eto eyẹ ifi iwe ẹri fun awọn akẹkọ isẹ olọpa ni ile ẹkọ awọn ọlọpa ni Ikẹja

Ọgbẹni L O Edet tun fun awọn akẹkọ ọlopa na opa fun lilo ni isẹ ọlọpa Oga agba awọn Ọlọpa na si fi fun awọn akẹkọ ọlọpa na ni ọrọ iwuri

### MOGADISHU

Ijọba apapọ ilẹ German ti şe adehun lati ya £875, 000 fun eto idagbasoke ilu awọn Alakoso eto owo ti Ijọba ilẹ German Haji Abdullahi ati aşuju ilẹ German lo si fi ọwọ si adehun na

### KATSINA

Ipade ọjọ meji fun ẹkọ kan si bẹre ni ilu-Katsina fun awọn Oşişe Ijoba Ibilẹ fun ogun ile işẹ Ijoba Ipinle Ariwa ilẹ Naijiria si ti nlọ deede ni Ile Ikawe ti ilu Katsina ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria bayi.

Ọpọlọpọ awọn eto ẹkọ to jẹmọ ti ile işẹ Ijọba Ibilẹ ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ni nwọn yio si yẹ awọn Oşişẹ ile işẹ Ijọba Ibilẹ to lọ fun eto ekọ na

### MOSCOW

Alakoso Ijọba Ilẹ Moscow Ọgbẹni Krushehev ti şe ikede kan lori eto lati le jẹ ki eto işẹ ọgbin ni ilọsiwaju. Ọgbẹni Khrushchev si ti pe awọn igbimọ na lati ile işẹ akoso eto ogbin ni Saratov lati le jẹ ki ilọsiwaju wa lori eto isẹ na ati lati le jẹ ki eto na yọri si rere

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 766 MONDAY, AUGUST 10, 1964 (2D)


## Okunrin Kan Pokunso

**BENDE:-** Ni ọjọ Eti ti iṣe ọjọ Keje oṣu yi ni Ọkunrin agbẹ kan ọgbẹni Koko Ọta eni ọdun metadinlogbọn lo pokunso ni inu igbo kan lẹba ilẹ ni Ndi-Oym Amẹkẹ Aban ni agbegbe Bende ni ipinlẹ Ila orun Naijiria.

Nigbati awọn enia to wa ni ilu ọgbẹni koko ota ni Ndi-Oyom Mẹmeke Aban bẹrẹ si wa Ọkunrin na kakari ti nwọn si tun bere si ni wa awọn igbo to wa ni tosi ilu na ni awọn enia kan ti nwọn tun bẹrẹ si wa igbo ṣuru kan to wa ni ẹba ilẹ ọgbẹni na ba fi igbe ta ti nwọn si ri Ọkunrin na to ti pokunso lara igi kan to wa ninu igbo na,

Irohin na tun fi ye wa pe orukọ Ọkurin to lọ pokunso ni Ọgbẹni Koko Ọta ba Ọkunrin kan ja ti o jẹ arugbo agbẹ kan ti orukọ rẹ njẹ Kalu Iyieke ẹni ọdun mejidinlogọta

Nigbati Ọgbẹni Ọta timọ pe okunrin na wa ni kojẹ oku tabi alaiye ni Ọgbẹni Koko Ọta ba lu igbo titi awọn enia bẹrẹ si wa kiri titi nwọn fi ba oku rẹ pade ti o ti pokunso.

## Ọlọpa Gb'ogun Ti Awọn Ọmọ L'ẹhin Oloye Awolọwọ

Lati Oju Ewe Kini

maṣe gbọ ẹbẹ awọn agbẹjoro na ti nwọn sọ pe ki Balewa o wa si kotu, on awọn ọlọpa mọ iṣẹ won nwọn si nse e gẹgẹbi iṣẹ, nitorina enikẹni ko tun ṣẹ ṣẹ le fi ọna iṣẹ ofin han wọn mọ.

Lẹhin eyi, ni adajọ ba paṣẹ pe on gba iduro ọgbẹni Adam Ọtẹkọya lori igba pọnun (£200) o si kọ iduro awọn enia meji yoku.

Lẹhin eyi ni adajo wa yẹ ọjọ gbigbọ ejọ na si ọjọ mẹjọ. ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi Bi nwọn ba ti pari ọrọ na si, ẹo tun maa gbo ninu iwe Irohinwa

Oniwe Irohin wa Ejongboro ti o wa ninu Ile ẹjọ na fi ye wa pe, Irohin awọn Ọlọpa fi ye on pe awọn enia maruo ni awọn Ọlọpa mu.

Ọga awọn ọlọpa Ọgbẹni R E Ezekel Hart fi ye Ejo pe, awọn ọlọpa mu ọkurin kan ni Iddo ati ọkan ni ọna Ikorodu, Palm Grove, nigbati Balewa mbọ wa si Eko ti nwọn nkigbe 'Awo. Irohin awọn ọlọpa fi ye wa pe, awa ọlọpa tun mu Obirin kan ti o ṣiṣẹ akọwe ile iṣẹ awọn oyinbo elepo moto Eyi lo si mu ki awọn enia na di mẹjọ.

Irohin kan ti a gbo ni ibẹre oṣu yi, ni wipe, "gbogbo awọn enia ti nwọn ba ti le darukọ Oloye Awolọwọ larin ilu ati paapa nigba Balewa ba nrekọja lọ larin ode ni awọn Ọlọpa yio maa mu

'Bi awọn Ọlọpa ba ti gbọ ti ẹnikan ba kigbe "Awo" nwọn omu oluwarẹ lọ si kotu fun pe, o fẹ ba alafia ilu jẹ"

Nitorina eyin ọmọ lẹhin Awolọwo ẹsọ di ọwọ nyin o agbọ wipe nwọn o fi oloye Awolọwọ silẹ laipe yi sugbọn a ko ti mọ ọjọ ti nwọn o fi silẹ.

Oniwe Irohin wa Ejonigboro yio lọ si Kalaba lai pẹ yi lati lọ foju kan Oloye Ọbafẹm Awolọwọ. Bi ohun ba si ti ri ẹo ma a gbọ o,

## A B'ọlọmọ Yọ Adefarakan Komọ Jade

EKO:- Irohin ko to afojuba, ọrọ si kọ afẹnusọ ni ase yẹ inawo ikomọjade ti ọmọ Ọba Adeniran Adefarakan ti gbogbo aiye mọ orukọ adapẹrẹ ni "Ẹrukobodo" ṣe ninu ile rẹ ni nomba 8, Idumọgbo Avenue, ni deede agogo mẹwa owurọ ana ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kansan oṣu yi.

Onirohin wa Ejongboro ti o lọ sibi inawo na lana fi ye wa pe, nigbati o ti ku bi ọjọ marun ni awọn enia ti bẹrẹsi de lati Ile-Ife Modakẹkẹ, Edun-Abọn, Ipetumodu' Ifẹtẹdo, Oke-Igbo Akomu, Aṣipa, Akiolalu, Moro, Yakoyọ ati bẹbẹ lọ

Ni deede agogo mẹsan owurọ ana ni ẹṣẹ gbogbo awọn Sanmọri, gbajumọ, oloye, Minista ati awọn enia sarakisaraki ti pe sansa sile baba ọmọ na.

Orukọ awọn ọmọ mejeji ti ba na ko jade ni Risikatu Aṣabi Nihinlade Adefarakan ati Nọusuratu Adenrele Adefarakan.

Lẹhinti awọn enia na ti ṣe adura fun awọn ọmọ na tan ni nwọn ba bẹrẹsi ijẹ, ti nwo si tun nmun. Bi nwọn ti nla emi, bẹni nwọn nla ata.



Ọgbẹni Adefarakan
Baba Ioko

Nigbati awọn enia na ti jẹ nkan sara tan ni gbogbo awọn alabaṣẹyẹ na wa njo bi kokoro kakiri gbogbo ad gbo ti gbogbo ara ọja Jankara ṣi fi igba ọja wọn silẹ ti nwọn yọ ayọ ọmọ na Gbogbo awọn enia ti ko wa ni nwọn gbe onjẹ lọ ba wọn nile ati ni arin ọja ni ana, ti gbogbo le si ndun yungba gẹgẹbi ọdun keresimesi.

A fi ẹniti ko kọja ni adugbo na lana ni ebi pa, Irohin na kan momọ, ole gongo gbọmọ kuro lori ẹni mo fẹ tẹ nkan, afi ẹniti yio ba tẹ gbese. Ah! inanwo na kọyọyọ ẹnu ko gba irohin, a fi ẹniti odebẹ lo le sọ.

Diẹ ninu awọn enia jankanjanka ti nwọn wa sibi inanwo na lana ni wọnyi Iyaafin Amọti Oshodi, Sadatu Sasọrẹ, Feyihara Gbaja, Ashakẹ Smith. Suwebatu Giwa, Jarinatu Finnih, Humuheri Awẹlẹnjẹ Mọriamọ Sule, Iyaafin Amudatu Mabayọmijẹ Ọmọ Ọba Anidu Akinyẹmi Hadji Yesuf Adeṣina Hadji A. K. Bella, Hadji Y K Yakubu. (Gen. Sec U M C) Hadji J Salu, (Naijiria U M C) A A Ọlayẹmi, R S Ọlawale, J A Parit, J Salami / B Akanmu Hadji-A.W.A Awẹlẹnjẹ, Fatai Kehinde Hadji Sanusi Shaki Alfa Tẹslimi Nasiru S A Oshodi A M Mogaji Hadji A Ayọbiojọ Hadji Se fudeen Alabi. Sikiru Lami' Abdul Tọlọruniomashọ.

Ki Ọlọrun da ọmọ awọn ọmọ na si ki o ṣọ awọn alaboyun leru kalẹ ki o si pese fun awọn ala ni Amin o


## GBIYANJU LATI LO:-

AWỌN EGBOGI IKỌ PATAKI MIRAN TI OWO WỌN POJU TI WỌN SI LAGBARA GIDIGIDI PẸLU:—

Ekini:- THYMO-EPHEDRINE SYRUP

Ekeji:- LINITUS SYRUP

AKIYESI PATAKI:— Maṣe bu ju ṣibi ọmọde kekere kan lọ ni ẹmeta lojumọ gẹgẹbi wọn ti ko si ara igo wọn nitori won lagbara pupọ, wọn ki si nṣe ara awọn ogun Ikọ Rọbirọbi ti wọn nta kakiri Igboro ilu Eko.

Bere egbogi wọnyi ni Ṣọbu:

WATERLOO MEDICINE STORES,
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji)



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 10/8/64.